# IṢẸ-IRANṢẸ PAULU NI MELITA ATI ROMU

**Iṣe Awọn Apọsteli 27:1-44; 28:1-31**

**ẸKỌ 371 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Wasu ọ̀rọ na; ṣe aisimi li akokò ti o wọ̀, ati akoko ti kò wọ̀; baniwi, ṣe itọ́ni, gbà-ni-niyanju pẹlu ipamọra ati ẹ̀kọ́ gbogbo" (2 Timoteu 4:2).**

**I Irin-Ajo ti o Lewu**

1 A fi Paulu ati awọn onde miiran le balogun ọ̀rún lọwọ ẹni ti o gbọdọ mú wọn lọ si Romu, Iṣe Awọn Apọsteli 27:1; 26:32

2 Balogun ọ̀rún ṣe inu-rere si Paulu, Iṣe Awọn Apọsteli 27:3; 24:23; 28:16, 30, 31

3 Ẹfufu lile dá ọkọ̀ Paulu duro pupọ, lopin rẹ ó si fọ si erekuṣu Melita, Iṣe Awọn Apọsteli 27:1-20, 27-44; 28:1

4 Paulu ti gba balogun ọrún ati ọga ọkọ̀ ni imọran pe ki wọn má ṣe ṣi ọkọ̀, ṣugbọn wọn kọ imọran rẹ̀, Iṣe Awọn Apọsteli 27:10, 11, 21

5 Oluwa fi Paulu lọkan balẹ wi pe ki yoo si ofò ẹmi, ṣugbọn wọn yoo padanu ọkọ̀ naa, Iṣe Awọn Apọsteli 27:22-26; Luku 8:23-25; Orin Dafidi 107:25-30

**II Irin-Ajo lati Melita lọ si Romu**

1 Ni Melita Ọlọrun wà pẹlu Paulu ni pipa a mọ́ lọwọ ejo oloro, ati ni mimu awọn alaisàn lara dá, Iṣe Awọn Apọsteli 28:1-10; Marku 16:17, 18

2 Awọn arakunrin ti o wà ni Puteoli ati awọn arakunrin ti o pade rẹ̀ ni Romu mú Paulu lọkàn le, Iṣe Awọn Apọsteli 28:11-15

3 A gba Paulu laye lati maa gbé ile agbawọ rẹ̀ ni Romu fun ọdun meji; nihinyii ni o si n waasu Ihinrere, kò si ẹni ti o di i lọwọ, Iṣe Awọn Apọsteli 28:16, 30, 31

4 Paulu bá awọn Ju ti o wà ni Romu fi ọ̀rọ wé ọ̀rọ, ṣugbọn pupọ ninu wọn kò gbagbọ́, Iṣe Awọn Apọsteli 28:17-29

## ALAYE

### Rirú Omi

Irin-ajo Paulu si Melita ati bi o ti pari si rirì ọkọ̀ jẹ́ itàn ti o kún fún ẹkọ pataki. O jẹ ohun ti o lewu lọpọlọpọ lati kọ imọran Ọlọrun. Paulu ti gba balogun ọrún abẹ itọju ẹni ti oun wà ni imọran pe irin-ajo naa yoo kún fún ewu pupọ bi wọn ba lọ ni akokò naa. Paulu wà ni irẹpọ̀ pẹlu Oluwa, nitori naa imọran rẹ̀ yẹ fun ohun ti wọn gbọdọ gbà rò gidigidi. Ṣugbọn balogun ọ̀rún naa yàn lati feti si ti ọga-ọkọ̀, wọn si bẹrẹ irin-ajo wọn. Bi o ti lẹ ri bẹẹ, opin irin ajo wọn jẹri si otitọ ohun ti Paulu sọ fun wọn. Wiwà ti Paulu wà ninu ọkọ̀ ni o mú ki Oluwa dá ẹmi awọn ti o wà ninu ọkọ̀ naa si laaye.

Nitori iba olododo diẹ, Ọlọrun maa n dá ẹmi ọ̀pọlọpọ si gẹgẹ bi Ọlọrun ti ṣeleri nigba ti Abrahamu n bẹ Ọlọrun nitori Lọti arakunrin rẹ̀ (Ka Gẹnẹsisi 18:20-32). Nitori ti o jẹ ifẹ Ọlọrun pe ki Paulu duro niwaju Kesari ati awọn ọba, Ọlọrun dá ẹmi rẹ̀ si. Nitori aawẹ ati adura Paulu fun idasi ẹmi awọn ti o wà ninu ọkọ̀ pẹlu rẹ̀, Oluwa dá wọn si, ẹnikan ninu wọn kò si ṣegbé.

Ọlọrun nikan ni o mọ iye igba ti O ti yọ awọn eniyan ayé kuro ninu wahala ati iparun nitori adura ẹ̀bẹ awọn eniyan Ọlọrun ti o wà laaarin wọn. Ọlọrun nikan ni o mọ iye awọn alafara ti o ti dá silẹ lọwọ ikú nitori adura awiyannu awọn Onigbagbọ́.

Otitọ yii kan naa ni Isaiah mu jade ninu ọ̀rọ rẹ̀ nigba ti o wi bayii pe, "Bayi ni OLUWA wi, gẹgẹ bi a ti iri ọti-waini titun ninu idi eso àjara, ti a si nwipe, Máṣe bà a jẹ nitori ibukun mbẹ ninu rẹ̀: bẽli emi o ṣe nitori awọn iranṣẹ mi, ki emi o má ba pa gbogbo wọn run" (Isaiah 65:8).

Boya awọn kan le beere bayii pe bi o ba ṣe ifẹ Ọlọrun ni fun Paulu lati lọ si Romu, ki ni ṣe ti O fi fi àye silẹ fun iji lati rì ọkọ̀ Paulu niwọǹ bi Oun paapaa ni Oluwa iji? Iwe Mimọ́ fi idahun si iru ijiyan

bayii pe, "Awamáridi idajọ rẹ̀ ti ri, ọ̀na rẹ̀ si jù awari lọ! Nitori tali o mọ̀ inu Oluwa? Tabi tani iṣe igbimọ rẹ̀?" (Romu 11:33, 34).

Lẹyin ti Oluwa ti kilọ fun Paulu nipa irin-ajò naa, Paulu gba balogun ọrún ni imọran ki o ma ṣe ṣikọ. Lọrọkan wọn bẹrẹ irin-ajo oju omi naa, sibẹ aanu Ọlọrun ti o wà lati ayeraye dé ayeraye wá sori awọn eniyan wọnyii, wọn si yọ bọ́ pẹlu ẹmi wọn. Lai si aniani, lẹyin iriri wọn, gbogbo awọn ti o wà ninu ọkọ̀ ni idaniloju oore-ọfẹ Ọlọrun ti n gba ni là. Nipa oore-ọfẹ yii ni awọn ara erekuṣu Melita fi gba Ihinrere, ti Paulu si wo àrun wọn sàn, eyi ti ki bá ti ṣeeṣe bi o ba ṣe pe ọkọ̀ kò ri Paulu ni erekuṣu naa. Lẹẹkan si, ọ̀rọ Iwe Mimọ́ ṣẹ ti o wi pe "Ohun gbogbo li o nṣiṣẹ pọ̀ si rere fun awọn ti o fẹ Ọlọrun, ani fun awọn ẹniti a pè gẹgẹ bi ipinnu rẹ̀" (Romu 8:28).

Nigba ti ẹnikan ba n ṣe ifẹ Ọlọrun gẹgẹ bi o ti wà ni ipa rẹ̀ lati ṣe, Ọlọrun yoo jẹ́ aabò fun un. Ririì ọkọ̀ ati gbogbo ewu ti n tẹle e kò pa Paulu lara, bẹẹ ni paramọlẹ ti o di mọ ọ lọwọ lojiji, kò ṣe e ni ibi rara. Ki i ṣe pe Paulu ni agbára kan funra rẹ̀ lati pa oro ejò naa, ṣugbọn nitori pe agbára Ọlọrun ti o bori ohun gbogbo sọ oró rẹ̀ di asán. Jesu ti ṣeleri pe: "Nwọn o si ma gbé ejò lọwọ; bi nwọn ba si mu ohunkohun ti o li oró, ki yio pa wọn lara rara" (Marku 16:18). Ohun ti Ọlọrun ba ti ṣeleri, yoo mu un ṣẹ. Awọn miiran ti ló ẹsẹ Ọ̀rọ Ọlọrun yii lọrun, lati fi hàn pe awọn le mọọmọ gbé ejo oloro lọwọ nitori pe wọn ka a si ojuṣe Ọlọrun lati má jẹ ki o pa wọn lara. Pupọ awọn eniyan ni o ti tumọ Ọrọ Ọlọrun lodi, ti wọn si ti gbé ejo lọwọ nireti pe Ọlọrun kò le ṣe alai daabo bò wọn, gẹgẹ bi ileri Rẹ̀. Iru awọn ti n fi ejo ṣere bayii ti kú nigba ti ejo bù wọ́n ṣán nitori wọn kugbu n reti aanu Ọlọrun lẹyin ti wọn ti ló otitọ́ Ọrọ Rẹ̀ si nnkan miiran. Ọlọrun pa Paulu mọ gẹgẹ bi O ti n pa awọn ti Rẹ̀ ti ejo bá ṣeeṣi bujẹ mọ́ tabi bi wọn bá ṣeeṣi mu ohun oloro.

Satani dán Kristi wò nipa fifi ẹsẹ Iwe Mimọ́ siwaju Rẹ̀ nipa iṣẹ ti Ọlọrun fi le awọn angẹli lọwọ nitori Rẹ̀ -- pe wọn yoo gbe e soke lọwọ wọn nigbakuugba ki o ma ba a fi ẹsẹ̀ gbún okuta. Ipinnu Satani ni lati dán Kristi wò ki O ba le bẹ́ silẹ lati ori ṣonṣo Tẹmpili lati fi hàn boya awọn angẹli yoo gbe E soke nitootọ ki O to ni ipalara, ati nipa bayii ki O le fi hàn nitootọ pe Ọmọ Ọlọrun ni Oun i ṣe. Ẹnikẹni ti o ba ṣi Ọrọ Ọlọrun lò lati le ṣe aṣeregé kan, kò wá aabo Ọlọrun bi kò ṣe pe o n dán Ọlọrun wò (Ka Matteu 4:5-7).

**Lilọ si Romu**

Kò si ohun pataki ti o ṣẹlẹ laaarin irin-ajo Paulu lati Melita lọ si Romu ṣugbọn ó bá awọn arakunrin pade lọna ti wọn fun un ni iṣiri. Nigba ti o de Romu, a gba Paulu laye lati maa gbé inu ile agbàwọ̀ fun ọdun meji. Bi o tilẹ jẹ pe a fi balogun ọrún kan ṣọ ọ, ti a si so ẹwọn mọ ọn, tabi ti a fi ẹwọn so o mọ́ balogun ọ̀rún naa, sibẹ a fun un laye lati gba gbogbo awọn alejo ati awọn ẹni ti o tọ ọ wá. Siwaju si i a kò di i lọwọ lati waasu Ihinrere.

Kaka ki ifisinu tubu jẹ́ idiwọ fun Paulu, ṣe ni o jẹ́ iranlọwọ fun un lati tubọ tan Ihinrere kalẹ ni Romu ati agbegbe rẹ̀. Ile rẹ̀ di olu-ilu fun ọ̀pọlọpọ iṣẹ itankalẹ Ihinrere. Lati ibẹ ni o ti kọ Episteli rẹ̀ si awọn ara Efesu, awọn ara Filippi ati si Filemoni. Paulu kọ iwe si wọn pe oun jẹ́ ikọ̀ ninu idè; bẹẹ ni o si jẹ́ ninu ẹmi ati ninu ara. O wà ninu idè ifẹ si Oluwa rẹ̀, o si wà ninu idè ti ara nitori ifẹ rẹ̀ ati isin fun Oluwa rẹ̀ (Wo Efesu 6:20). Pẹlu igbagbọ pipe ninu iṣẹ Ọlọrun ni igbesi-ayé rẹ̀, Paulu ka ifisinu-tubu rẹ̀ gẹgẹ bi eto Ọlọrun fun un, o si kọ iwe si ijọ Filippi bayii: "Njẹ emi fẹ ki ẹnyin ki o mọ̀, ará, pe nkan wọnni ti o de bá mi, o kuku yọri si ilọsiwaju ihinrere; tobẹ ti idè mi gbogbo farahan ninu Kristi larin awọn ọmọ ogun ãfin ati gbogbo awọn ẹlomiran" (Filippi 1:12, 13).

Paulu le ri i pe Ọlọrun jẹ́ ayinlogo nipa idè rẹ̀. Ogunlọgọ awọn ti kò ba ti mọ Oluwa ni o n ri iṣẹ Oluwa ni ojukoju ti wọn n pade ti wọn si n ri awọn wọnni ti n ba Paulu pejọ lojoojumọ. Ojoojumọ ni awọn ti o wà ni aafin n ri iyatọ laaarin igbagbọ́ ẹni iwa-bi-Ọlọrun ati ìwa ẹ̀ṣẹ ati ọ̀na ibọriṣa awọn ara Romu ati ìwa ibajẹ awọn ọba wọn. Laaarin ilu ti o kún fun ẹ̀ṣẹ ni a ti waasu Kristi ti ọ̀pọlọpọ ọkàn si n ri igbala. Paulu jẹ́ onde ti Romu sibẹ Ọlọrun tẹri awọn alagbara ilu naa ba si ifẹ Rẹ̀, O si mú ki Paulu ki ṣe aṣeyọri ninu iwaasu rẹ̀ ni aafin awọn Kesari (Wo Filippi 4:22). Bi Paulu ti n ṣe aṣaro nipa iṣẹ Ọlọrun, o tẹ̀ siwaju ninu ọ̀rọ iyanju rẹ̀ bayii pe: "Ọ̀pọlọpọ awọn arakunrin ninu Oluwa, ti o ni igbẹkẹle si ìde mi nfi igboiya gidigidi sọrọ Ọlọrun laibẹru. Nitotọ awọn ẹlomiran tilẹ nfi ija ati ilara wasu Kristi; awọn ẹlomiran si nfi inurere ṣe e. Awọn kan nfi ìja wasu Kristi, kì iṣe pẹlu õtọ inu, nwọn ngbiro lati fi ipọnju

kún ìde mi: awọn kan ẹwẹ si nfi ifẹ ṣe e, nitoriti nwọn mọ̀ pe a gbe mi dide fun idahun-ẹjọ ihinrere. Njẹ kini? bikoṣepe nibi gbogbo, iba ṣe niti agalamaṣa tabi niti otitọ, a sa nwasu Kristi; emi si nyọ̀ nitorina, nitõtọ, emi ó si ma yọ̀" (Filippi 1:14-18).

Paulu fi apẹẹrẹ igboya ninu ide hàn, o si kún fún itara ati igbagbọ́ ninu Ọlọrun eyi ti o rú ọ̀pọ ọkàn soke lati doju kọ ipenija Ihinrere. Bi o tilẹ jẹ pe awọn ọta n dide pẹlu èro lati di Paulu lọwọ ati lati pa a lara si i, sibẹ ṣe ni eyi fun un ni ipá lati waasu Ihinrere jù bẹẹ lọ. Ayé, ara ati eṣu ti n wá ọ̀na lati igba ti Adamu ti ṣẹ̀, lati dena, lati sé Ihinrere Jesu Kristi mọ́ ati lati sọ ọ di alailagbara. Nipa pipa awọn oniwaasu rẹ̀, wọn rò pe awọn yoo fi opin si gbigbọ́ ohùn Ọlọrun, ṣugbọn si iyalẹnu wọn, wọn ri pe Oluwa le mu ki awọn okuta maa yin Oun ki wọn si maa ba iṣẹ Oun lọ.

Iwe Iṣe Awọn Apọsteli jẹ́ akọsilẹ awọn eniyan Ọlọrun ti o ni igboya nla ninu Oluwa wọn, ti wọn si n yọ̀ ninu igbala ti O mú wá fun wọn, wọn lọ si gbogbo ayé lati waasu Ihinrere Jesu Kristi ti a kàn mọ́ agbelebu. Jẹ́ ki awọn Onigbagbọ́ ode-oni ni igboya ninu igbagbọ́ wọn gẹgẹ bi awọn Apọsteli igbaanì, awọn ti kò bẹru eniyan tabi eṣu ti o doju kọ wọn ṣugbọn ti wọn n ṣafẹri ifohun si ati iyin Oluwa wọn nikan fun ere wọn. Wo bi awọn ọ̀rọ ti a fi pari Iwe Iṣe Awọn Apọsteli ti ṣe rẹmurẹmu tó! Ẹni ti o kọ iwe yii sọ bi Paulu ti "nwasu ijọba Ọlọrun, o si nfi igboiya gbogbo kọ́ni li ohun wọnni ti iṣe ti Jesu Kristi Oluwa, ẹnikan kò da a lẹkun" (Iṣe Awọn Apọsteli 28:31).

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni ṣe ti a fi n mu Paulu lọ si Romu?

2 Bawo ni balogun ọrún labẹ ẹni ti Paulu wà ṣe ṣe itọju rẹ̀?

3 Ki ni ṣe ti Paulu fun balogun ọrún naa ni imọran pe ki wọn ma ṣe ṣikọ ni akoko naa?

4 Irú irin-ajo wo ni wọn ni?

5 Ta ni ẹni ti o gba awọn ti o wà ninu ọkọ naa là?

6 Ki ni o ṣẹlẹ si Paulu ni Melita ti o fi idi otitọ ọrọ Kristi mulẹ?

7 Bawo ni awọn ara Romu ṣe ṣe itọju Paulu?

8 Bawo ni aṣeyọri Paulu ti pọ̀ tó ninu iwaasu rẹ̀ ni Romu?

9 Bawo ni Paulu ṣe le waasu nigba ti a de e mọ́ ọmọ-ogun Romu kan?

10 Darukọ meji ninu awọn Episteli ti Paulu kọ nigba ti o wà ninu ile tubu.